EFF'S SURVEILLANCE SELF-DEFENSE

# BÍ A ṢE Ń: FO ÌTẸRÍBỌLẸ̀ AYÉLUJÁRA DÁ

*https://ssd.eff.org/en/about-surveillance-self-defense*

LOCALIZATION LAB

# Bí a ṣe ń: fo ìtẹ́ríbọlẹ̀ Ayélujára dá

Ìİtúnwò Ìkẹyìn:
8-10-2017

Èyí ni àkótán kúkúrú nípa ìfòdá ìtẹ́ríbọlẹ̀ orí ayélujára, ṣùgbọ́n kì í ṣe ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.

Ìjọba, ilé-iṣẹ́, ilé-ìwé, àti apèsèe ẹ̀rọ-àìrídìmú tí yóò dí òǹlò lọ́wọ́ kí wọ́n ba máà rí ààyè wọ àwọn ibùdó-ìtàkùn kan. Èyí ni a pè ní ìsẹ́ ẹ̀rọ-ayélujára tàbí ìdígàgá, tí í ṣe irúfẹ́ ìtẹ́ríbọlẹ̀ kan. Onírúurú ìsẹ́ ló wà. Atẹ́ríbọlẹ̀ẹ́ lè dígàgá ojú ìwé ìtàkùn-àgbáyé kan ṣoṣo tàbí gbogbo ibùdó-ìtàkùn-àgbáyé pọ̀. Nígbà mìíì, ohuninú ojú ìwé orí ayélujára ní í máa ń fa ìdígàgá

Onírúurú ọ̀nà ni a fi lè fo ìtẹ́ríbọlẹ̀ orí ayélujára dá. Àwọn kan ń fi ààbò ìṣọ́ni bò ọ́, ṣùgbọ́n ọ̀pọ̀ ò ṣe bẹ́ẹ̀. Bí alákòóso ìṣàsopọ̀ ayélujáraà rẹ bá ṣẹ́ tàbí dígàgá ibùdó kan, o lè lo irinṣẹ́ ìfòdá tí yóò mú ọ rí ìwífún tí o nílò.
Fiyèsíi: irinṣẹ́ ìfòdá aṣèlérí ààbò tàbí ibi-ìkọ̀kọ̀ kì í sábà í ṣe ti ìkọ̀kọ̀ tàbí ní ààbò. Irinṣẹ́ tó ń lo gbólóhùn bíi "anonymizer" kì í sábà pa ìdánimọ̀ọ rẹ mọ́ fínnífínní.

Irinṣẹ́ ìfòdá tó dára jù fún ọ dá lóríi àwòṣe ìdẹ́rùbà rẹ. Bí àwòṣe ìdẹ́rùbà rẹ ò bá dá ọ lójú ṣáká tó, bẹ̀rẹ̀ níhìn-ín.

Nínú àpilẹ̀kọ yìí, a máa sọ̀rọ̀ nípa ọ̀nà mẹ́rin tí a lè gbà fo ìtẹ́ríbọlẹ̀ orí ayélujára dá.

- Bíbẹ aṣojú ìtàkùn wò láti wọ ibùdó-ìtàkùn tí a ti dígàgáa rẹ̀.
- Bíbẹ aṣojú ìtàkùn tí a ti yí dátà rẹ̀ padà sí odù ààbò láti wọ ibùdó-ìtàkùn tí a ti dígàgáa rẹ̀.
- Lílo Ìṣàsopọ̀ Àìrí Ìkọ̀kọ̀ (VPN) láti wọ ibùdó-ìtàkùn tàbí iṣẹ́.
- Lílo aṣàwákiri Tor láti wọ ibùdó-ìtàkùn tí a ti dígàgáa rẹ̀ tàbí dáàbò bo ìdánimọ̀ọ rẹ.

# Àwọn ìpìlẹ̀ ìmọ̀

Iṣẹ́ tí irinṣẹ́ ìfòdá sábà máa ń ṣe ni dídaríi dátà tó ń gba orí ìtàkùn rẹ kí o ba yẹ ẹ̀rọ tó ń ṣe ìdígàgá tàbí ìsẹ́ kúrò. Iṣẹ́ tí í ṣe àtúndaríi ìṣàsopọ̀ ayélujára fo ìdígàgá kọjá là ń pè ní aṣojú ń'gbà mìíì.

HTTPS ni ẹ̀dà ààbò fún ìfẹ́nukò HTTP tí ò ń lò fi wọ ibùdó-ìtàkùn-àgbáyé. Nígbà mìíràn Atẹ́ríbọlẹ̀ẹ́ lè dígàgá ẹ̀dà ibùdó àìláàbò (HTTP). Ìyẹn ni pé o lè wọ ibùdó tí a dígàgá náà bí o bá tẹ ẹ̀dà àdírẹ́ẹ̀sì ibùdóò rẹ tó bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú HTTPS.

Èyí wúlò bí ìtẹ́ríbọlẹ̀ tí ò ń bá kòdìmú bá dígàgá ojú ìwé ìtàkùn-àgbáyé kan ṣoṣo látàrí ohuninúu rẹ̀. HTTPS máa ń dá atẹ́ríbọlẹ̀ dúró láti máà le è ka dátà tó ń gba oríi ìtàkùn rẹ, torí náà wọn kò le è sọ ọ̀rọ̀-aṣínà tí a fi ránṣẹ́, tàbí orí ojú ìwé ìtàkùn-àgbáyé tí ò ń bẹ̀wò.

Atẹ́ríbọlẹ̀ ṣì lè rí orúkọ agbègbè ìkápáa gbogbo ibùdó-ìtàkùn-àgbáyé tí o bá lọ. Fún àpẹẹrẹ, bí o bẹ "eff.org/https-everywhere" wò atẹ́ríbọlẹ̀ lè rí i wípé o wà lóríi "eff.org", ṣùgbọ́n kì í ṣe pé o wà lórii ojú ìwée "https-everywhere."

Bí o bá ní ìfura irúfẹ́ ìdígàgá àìle báyìí, gbìyànjú kí o tẹ https síwájú agbègbè ìkápá dípò http

Gbìyànjú kí o gbé alátànkáa EFF ibi-gbogbo tí yóò fúnra rẹ̀ tan HTTPS níbi tó bá yẹ sórí ẹ̀rọ̀ọ̀ rẹ.

Ọ̀nà mìíràn tí o lè gbà fi fo ìtẹ́ríbọlẹ̀ dá ni bí o bá lo orúkọ agbègbè-ìkápá mìíràn tàbí URL. Fún àpẹẹrẹ, kàkà kí o bẹ http://twitter.com wò, o lè gbìdánwò láti ṣí ibùdó náà lóríi ẹ̀dà ti ẹ̀rọ-ìbánisọ̀rọ̀ alágbèéká ní http://m.twitter.com.
Atẹ́ríbọlẹ̀ tó dígàgá ibùdó-ìtàkùn-àgbáyé tàbí ojú ìwé ìtàkùn-àgbáyé ń fi àkàsílẹ̀ ibùdó-ìtàkùn-àgbáyé àìdára tí a ti gbẹ́sẹ̀ òfin lé ṣiṣẹ́, torí náà ohunkóhun tí kò bá sí lórí àkàsílẹ̀ àìdára yẹn yóò la ìtẹ́ríbọlẹ̀ kọjá.
Wọ́n lè máà mọ gbogbo onírúurú ẹ̀dà orúkọ ibùdó-ìtàkùn-àgbáyé ní pàtó - ju gbogbo rẹ̀ lọ bí alákòóso ibùdó bá mọ̀ wípé a ti dígàgáa rẹ̀ àti pé a orúkọ agbègbè ìkápá tí a fi sílẹ̀ ju ọ̀kan lọ.

## Aṣojú orí ìtàkùn-àgbáyé

Aṣojú orí ìtàkùn-àgbáyé (gẹ́gẹ́ bíi http://proxy.org/) jẹ́ ibùdó-ìtàkùn-àgbáyé tí ń f'ààyè gba òǹlò láti wọ ibùdó tí a dígàgáa rẹ̀ tàbí tẹ́ríi rẹ̀ bọlẹ̀. Ọ̀nà tó dára láti fo ìtẹ́ríbọlẹ̀ dá lèyí. Láti lo aṣojú orí ìtàkùn-àgbáyé, bẹ aṣojú náà wò kí o tẹ àdírẹ́ẹ̀sì ibùdó-ìtàkùn tí o fẹ́ rí sí i; aṣojú yìí yóò fi ojúùwé ibùdó-ìtàkùn tí o béèrè fún hàn ọ́.

Bótiwùkíórí, aṣojú orí ibùdó-ìtàkùn-àgbáyé kì í pèsèe ààbò kankan àti pé kò ní ṣ'ẹ̀nuure bí àṣàyàn àwòṣe ìdẹ́rùbà rẹ bá ní aṣọ́ní tí ń ṣọ́ ìṣàsopọ̀ rẹ. Wọn kò ní ràn ọ́ lọ́wọ́ láti lo iṣẹ́ tí a ti dígàgá gẹ́gẹ́ bíi ààpù iṣẹ́-ìjẹ́ oníwàràǹṣesà rẹ. Aṣojú orí ibùdó-ìtàkùn-àgbáyé máa ní àkọsílẹ̀ ohun gbogbo tí ò ń ṣe lórí ayélujára, tí ó lè jẹ́ ewu ìdáààbòbò fún òǹlò mìíràn lórí àwòṣe ìdẹ́rùbà wọn.

## Aṣojú tí dátà rẹ̀ ti yí padà sí odù ààbò

Ọ̀kẹ́ àìmọye irinṣẹ́ aṣojú tó ń lo ìyí-dátà-padà-sódù-ààbò láti pèsè ìpele ìròpọ̀ ààbò lórí agbára ìdákọjá ìsẹ́.

Ìṣàsopọ̀ náà ti yìí dátà padà sí odù ààbò kí ẹlòmíràn ó máà ba à lè rí ibi tí ò ń bẹ̀wò. Nígbà tí aṣojú tí dátà rẹ̀ ti yí padà sí odù ààbò l'áàbò tó péye ju aṣojú orí ìtàkùn-àgbáyé lọ, apèsè irinṣẹ́ náà lè rí ìwífún nípaà rẹ. Fún àpẹẹrẹ, wọ́n lè ní orúkọ àti àdírẹ́ẹ̀sì ímeèlì rẹ lákọsílẹ̀. Ìyẹ́n túmọ̀ sí wípé irinṣẹ́ wọ̀nwọ̀nyí kì í pèsèe àìlórúkọ dójú àlà.

Aṣojú ìtàkùn-àgbáyé tí dátà rẹ̀ ti yí padà sí odù ààbò tó rọrùn jù ni “https” - èyí yóò lo ìyí-dátà-padà-sódù-ààbò tí ibùdó-ìtàkùn-àgbáyé tó l'áàbò pèsè.
Síbẹ̀, ṣọ́ra - àwọn to ni aṣojú wọ̀nyí lè rí dátà tí o fi ránṣẹ́ sí àti bọ̀ wá láti ibùdó-ìtàkùn-àgbáyé ààbò mìíràn. UltraSurf àti Psiphon jẹ́ àpẹẹrẹ irinṣẹ́ báwọ̀nyí.

# Ìṣàsopọ̀ Àìrí Ìkọ̀kọ̀

Ìṣàsopọ̀ Àìrí Ìkọ̀kọ̀ (VPN) máa ń yí dátà padà sí odù ààbò, yóò sì fi gbogbo dátà ránṣẹ́ láti orí ẹ̀rọ-ayélujáraà rẹ sórí ẹ̀rọ ayárabíàṣá mìíràn. Ẹ̀rọ ayárabíàṣá yìí lè jẹ́ ti iléeṣẹ́ ìṣòwò kan tàbí ilé-iṣẹ́ àìjèèrè apèsèe VPN, ilé iṣẹ́ẹ rẹ, tàbí ẹni mímọ̀. Ní kété tí iṣẹ́ẹ VPN bá ti wà, o lè lò ó fi wọ ojú ìwé ìtàkùn-àgbáyé, ímeelì, iṣẹ́-ìjẹ́ oníwàràǹṣesà VoIP, àti iṣẹ́ orí ẹ̀rọ ayélujára tó kù. VPN máa ń dáàbò bo ìwífún tó ń kọjá lórí ayélujára kí àwọn alamí má ba à rí i lágbègbè kan, ṣùgbọ́n apèsèe VPN rẹ ṣì lè ṣe àkọsílẹ̀ ibùdó-ìtàkùn-àgbáyé tí o wọ, tàbí jẹ́ kí ẹnìkẹ́ta yọ́ kẹ́lẹ́ wọ inúu aṣàwáríkiri ayélujáraà rẹ.
Ó dá lóríi àwọ̀ṣe ìdẹ́rùbà rẹ, o ṣe é ṣe kí ìjọba ó máa fẹtíkọ́ ìṣàsopọ̀ VPN rẹ tàbí gbígbá àkọsílẹ̀ VPN rẹ mú lè di ewu ńlá. Fún ònlò mìíràn, èyí lè lágbára jù f'àǹfààní tó wà nínú lílo VPN fún ìgbà díẹ̀.

Fún àlàyé nípa àwọn iṣẹ́ VPN ní pàtó, ṣíra tẹ ibí

Ní EFF a kò le è jẹ́rìí sí VPN wọ̀nyí. VPN mìíràn tí ó ní ìlànà ààbò tó yàrá ọ̀tọ̀ lè jẹ́ ti ọ̀daràn. O kò gbọdọ̀ lo VPN tí o kò fi ọkàn tàn.

**Tor**

Tor jẹ́ iṣẹ́-àìrídìmú orísun-ìṣísílẹ̀ tí a ṣe kí ìdánimọ̀ọ rẹ ó ba wà nípamọ́ lórí ìtàkùn àgbáyé. Aṣàwáríkiri ìtàkùn-àgbáyé ni aṣàwáríkiri Tor tí a kọ́ sóríi ìṣàsopọ̀ àìlórúkọ ònlò Tor.
Nítorí bí Tor ṣe ń gbé dátà ká lórí aṣàwáríkiri ibùdó-ìtàkùn rẹ, ó gbà ọ́ láàyè láti fo ìtẹ́ríbọlẹ̀ dá. (Wo bí a ṣe ń: lo ìtọ́nà Tor fún Linux, macOS àti Windows)

Bí o bá ṣí Aṣàwáríkiri Tor, o lè ṣe àṣàyàn àfihàn wípé oríi ìṣàsopọ̀ tí a tẹ́ríi rẹ̀ bọlẹ̀ lo wà:



ÌTor kò ní fo ìtẹríbọlẹ̀ ọ̀pọ̀ ìlú kọjá nìkan, ṣùgbọ́n, bí o bá fàṣẹ fún un bí ó ṣe yẹ, ó lè dáàbò bo ìdánimọ̀ọ̀ rẹ kí ó máà bọ́ s'ọ́wọ́ ọ̀tá tó ń tẹ́tí sí ìṣàsopọ̀ ìlúù rẹ. Síbẹ̀, ó lè máa fà tìkọ̀, kò sì rọrùn ní lílò.

Láti ka bí o ṣe lè lo Tor lórí ẹ̀rọ ayárabíàṣá àgbélétábìlì, ṣíra tẹ ibí fún Linux, ibí fún MacOS, tàbí ibí fún Windows, àmọ́ jọ̀wọ́ rí i dájú wípé o f'ọwọ́tọ́ "configure" dípò "connect" nínú àwòrán fèrèsé òkè.